LAKAYE ORO

OJU Oluwa mbẹ lara awọn olododo eti Rẹ si si si igbe wọn. Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu lati ke iranti wọn kuro lori ile.

Awọn olododo nke Oluwa si gbọ, o si yọ wọn lade kuro ninu iṣe wọn gbogbo.


# Irohin Yoruba

NO. 776 APRIL 20 — APRIL 26, 1960 Kobo Meji (2D.)


OWE

A NJUWON ko se wi telo ija ilara ko tan boro

Agbalagba ti yio te ile tutu yio da omi siwaju. Igba ki i to lo bi orere aiye ki i to lọ bi opa ibon.

# ỌMỌ ILE IWE PA ẸKUN O SI DI ỌDẸ

AMỌDU LẸBA ỌFFA.

NI oruganjọ ọjọ 'Ru ti iṣe ogbonjọ oṣu ti o kọja yi ni ọmọ ile-iwekan ti oruwọ rẹ njẹ Samuel Jẹnyọ wa ki aburo iya rẹ ni "Amọdu" ọmọ ọdẹ gidi haunhaun ni ọdọmọde akẹkọ yi nṣe; eyi jẹki o ti gbọ ti ọdẹ ṣiṣe nigbati o ti gbọ ti awọn ọdẹ ti bẹrẹsi fun 'toromẹigbe" (fere ọdẹ) o ti mọ pe igbo ọdẹ ya niyẹn, o ta mọra o si gbe ibon aburo iya rẹ lọwọ, olukuluku si gẹgun koi ti to iṣẹju mẹwa ti nwọn to iṣẹju mẹwa, ti nwọn ti ti wọgbo lo ni o ri kini kan 'nu okunkun ti o ndan yẹnrẹnyẹnrẹn bi diamọndi ẹru nyo ọ ba o ṣebi iwinlẹ kan ni on ri. Gẹgẹbi iṣe ọmọde, o kan gbe ibon rẹ o yin si i ẹsẹkẹsẹ ni awọn ọdẹ yoku ti sure de ọdọ rẹ pe kilo de. kini o ri ti o fi nyinbọn o ni on si ri kannka ti o tan yẹnrẹnyẹnrẹn lọkọọkan ni, on mọ daju pe ki ṣe enia ẹru si ba on, on si ro pe awọn "'oro igi" ni otanna,ni on ba fi iberu bojo yinbọn si ọkankan ibẹ.

Loju kanna ni awọn ogbokangi ọdẹ ba bẹrẹsi tọ ipasẹ ibẹ lọ kugu ni pwọn kan Ẹkun ọlọla iju afame lori iyagbẹ ti o sun, bọlọjọ ninu agbara ẹjẹ atari rẹ si ti tuka yangayanga ha! ha! ṣe awọn ọdẹ yi nitoripe bi nwọn ti ṣe jẹ "ogbonkangi ọdẹ to, saṣa ni eyiti o pa ẹkun ri ninu won.

Nwọn gbe ekun na lọ si ile ti nwọn si ṣe etutu ti o yẹ ki nwọn ṣe! nwọn si fi jẹ oye ajinhanrin kan ninu awọn ọdẹ gẹgẹbi aṣa wọn.

Nigbati nwọn ṣe eto pinpin ẹran ẹkun na tan ti nwọn pejọ ti nwọn si bẹrẹsi ṣe aṣaro lori ọrọ ọmọde ti o pa ẹkun yi, ni nwọn ba fi ọmọde na jẹ Olu-ọdẹ, nitori ọdẹ ti o ba pa ẹkun nilati gba Oye Olu-ọdẹ. ni ọmọ ba di Oloye Olu-ọdẹ lati ile-iwe.



Oloye Akintola pẹlu Ataoja Oshogbo ni o wa ni ibẹrẹ ninu Mọsalasi Jimọ ti nwọn nkirun lọwọ yi nigbati Oloye Akintọla lọ ṣe idupẹ igorioye Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ - Orun ninu Mọsalasi na laipẹ yi.

## Boya Ọni Ifẹ ni yio di Gomina Ipinlẹ Iwo-Orun

O LE jẹ pe, Ọlọla Ọba Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi, Oni Ifẹ ni yio rọpo Ọlọla John Rankine, Gomini Ijọba Ibilẹ Iwọ-Orun nigbati aye Gomina na ba ṣi silẹ.

Idi ti o fi le jẹ bẹ e ni pe, awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ti ijanu akoso Ijọba Ipindẹ Iwọ-Orun wa lọwọ wọn ki iṣe nkankan tan ki nwọn to ro ọ, nwọn ma a nro dada ni ki nwọn to ṣe e.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Ijọba Apapọ Naijiria ti da nimoran fun awọn Igbimọ Apapọ na pe Ọba iṣẹdalẹ ilu Naijiria ni ki nwọn yan si aye Gomina Agba nigbati aye na ba ṣi silẹ.

## Oyin tu ọja hi Kuta

KUTA LẸBA MINNA.

NI deede agogo meji ọsan ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejọ osu yi ni awọn oyin oloro kan ya wọ oja-Kuta, nwọn si bẹrẹsi ta gbogbo enia ni atagba jo bẹ ẹ ti oja na fi tu lẹsẹkẹsẹ.

Ohun ti o fa a ti awọn oyin na-fi ya wọ ọja ni pe, nigbati obirin kan ti o fi ikoko gbe oyin wa ta lọja ṣi ọmọri ikoko na kuro, ti o si bẹrẹsi ta oyin sinu igo fun awọn ti o fẹ ra oyin, ni awọn oyin ba gbo oorun rẹ lati inu igbẹ, nwọn si lepa rẹ wa si ibiti o wa lọja.

Lọwọ kokoro oloro buruku bayi, Oluwa rere gba wa o.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Apapọ Ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ẹkun–Ọshun ṣẹyẹ nla fun Oloye Akintọla

OSHOGBO.

NI ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kesan oṣu yi ni Apapọ gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ẹkun Ọshun ṣe ẹyẹ nla kan ninu Ile-ere "Recreation Club" Oshogbo fun Oloye S. L. Akintọla, Gbakeji Olori Ẹgbẹ Afenifẹre ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lati fi ayọ wọn han aye Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o de, ati lati yin in nitori iṣẹ-iṣelu rere ti o nṣe.

Lẹhin ti nwọn ti ka Iwe-ẹyẹ ikini-kuabọ ti Oloye Tinubu gbe fun Oloye Akintọla ni orukọ ẹgbẹ na tan, ni Oloye Akintọla bẹrẹsi fesi si ọrọ apọnle na pe: "Ibukun nla ni Igbimọ Ijọba rere titun ti o fi ọrọ gbogbo ara ilu yi ṣọkan, ti o si ngmojuto o dada jẹ fun Ipinlẹ Iwọ-Orun ati paajulọ, fun Ẹkun Ọshun.

Oloye Akintọla si tun ṣe alaye pe, larin ọdun mẹwa sẹhin yi ni Ẹkun Ọshun ti gba aṣẹ akoso iṣelu si arin ara wọn, eyi ni o si fun wọn ni agbara lati le ma a da nkan ilu wọn ṣe. O ni awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ mọkanla ti o npaṣẹ Ẹkun Ọshun mọ pe awọn daduro lọtọọto ni, sibẹsibẹ, nwọn mọ wipe ẹnikọọkan pataki ti o to daduro ti a ko sile ya sọtọ ni wọn.

Lẹhin eyi ni AlakosoA Ijọba na wa mu oniruru awọn nkan idagbasoke-ilu ti o ti wa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun lati igbati Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti tẹwọgba Akoso Ijọba na wa si iranti pe. "Ki Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) to di Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun kosi titi ọlọda ẹyọkan ni Ẹkun Ọshun, ṣugbọn loni, titi ẹlọda ti o wa yika gbogbo ibẹ din diẹ ni ọoko-lerugba o din meji busọ (217½ miles) owo ti Ijọba si fi ṣiṣe busọ kọọkan to ẹgbẹẹdọgbọn ponun (£5,000), o si sọ wipe ọpọlọpọ titi ni o wa ninu eto titun ti Ijọba ṣẹṣẹ ṣe ti nwọn yio tun yọ ọda si.

**AFIKUN ETO ILERA**

Lori ẹran eto Ilera: Oloye Akintọla ṣe alaye pe, Ile-iwosan kanṣoṣo ni o ti wa ni Ẹkun na tẹlẹ ri, ṣugbọn loni, mẹta ni o wa nibẹ. O ni ko tilẹ si Ile amojuto eto Ilera Adugbo kan nibe tẹlẹri ni ọdun 1950 ṣugbọn loni, mẹfa ni o wa nibẹ. Ni nkan bi ọdun 1950, ki oto di igbati akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun bọ si ọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre. Ile ipo-oogun mẹfa pere ni o wa ni gbogbo ẹkun na, ṣugbọn loni, Ile ipo-oogun mẹtadiladọta ni o wa nibẹ. Ile itọju awọn aboyun ati abiamọ mẹta pere ni o wa nibẹ nigbana, o ti di mejilelogun loni.

**Owo ti Ijọba nya awọn Agbẹ ati Onisowo**

Nipa owo yiya: Oloye Akintọla ṣe alaye siwaju pe, larin ọdun mẹrin ti o kọja yi owo ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti ya awọn agbẹ to ọkẹ-mẹrin le ọrinlerugba o din meji ponun (£80,278). Larin ọdun marun sẹhin, owo t io ya orisirisi awọn ti o da iṣẹ owọ silẹ to ọkẹ-meji le lẹgbẹrin o din mẹkanleladọta ponun (£40,749).

Nipa Ẹkọ: Oloye Akintọla so wipe, ko si ẹyọ Ile ẹkọ giga (Grammar School) kanṣoṣo ni gbogbo Ẹkun Oshogbo ninu ọdun 1950, ṣugbọn, loni, Ile-ẹkọ giga merindilogun ni o wa nibe. lẹhin gbogbo nkan wọnyi Ijoba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni o nsan owo-osu fun gbogbo awọn olukọ ti o nṣiṣẹ ninu wọn, ọgbọn Ile-iwe Giga **Secondary Modern Schools** ni o wa nibẹ nisisiyi. bẹni ko si ẹyọkan nibẹ tẹlẹri Alakoso Ijọba na si tun fi kun ọrọ rẹ pe: Ile-ẹkọ Gigajulọ fun awọn ti o nkọṣẹ olukọ (Teachers' Training College) mejọ fun awọn apa keji (Grade II) ati apa kẹta (Grade III) awọn akẹkọ ni nwọn ti kọ si Ẹkun Ọshun nisisiyi

Ninu Iwe-ẹyẹ ikini-uabọ ti nwọn fi yẹ Alakoso Ijọba na si, nwọn ṣe apejuwe pe: "Oloye Akintọla ni ojulowọ ọmọ Ọshun ti o peye julọ" lẹhin eyi, nwọn fi agbada asọ-oke nla kan ti o joju ta a lọrẹ, Iyaafin Adejumọ si fi akukọ adiẹ kan ta a lọrẹ pẹlu.

## AKIYESI FUN ONKAWE

Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin o n k a w e ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o ma a kọ ọ taara si ile iṣẹ re ni:

Amalgamated Press Ltd.,
5/7, Apọngbọn Street,
P. O. Box 163, Lagos.


**O npese agbara ọla silẹ**



Orun asunwọra ti ko ba mu iyọnu dani nsọ gbogbo agbara ati okun-inu di ọtun. Agbara titun ati okun-inu a si wa fun ọjọ keji. Eyi ni o mu ki ogunlọgọ awọn ọlọmọ-lẹbi fi ma a mu Ovaltine ki nwọn to sun lalẹ. agbara titun-ẹjẹ-ṣe rẹ a ma a mu ara sile a si jẹki enia le sun asunwọra gẹgẹbi o ti yẹ, wa a ji pẹlu ara-yiya ati pẹlu ẹmi akotun ati ara lile. Ovaltine olokiki ti gbogbo aiye ti mọ jẹ onjẹ—mimu aladun ti o ntun ẹjẹ ṣe.

**OVALTINE**




*Ara lile ti o nfun ni ko lẹgbẹ*

# ẸNI TI KO FẸNI, AALỌ KO RAN AN

OLOTU Irohin Yoruba, oju nyin ko ni ri ibi lagbara Edumare Itan kekere kan ni a nfẹ fi ṣe eṣin-ọrọ wa toni o, ẹnyin ara ile.

**ỌBA BI ỌMỌKUNRIN KANṢOṢO**

Ni akoko kan, nigba lailai, ọba kan wa ninu ilu kan. Ọla Ọba yi pọ to bẹ ẹ depo wipe, o fẹrẹ ma le mọ iye ilu ti o wa ni abẹ akoso rẹ tan, aṣẹ ti Ọba yi ba si pa na ni yio mulẹ lati iwaju aiye titi de ẹhin aiye. Bayi ni ọla ọba yi nfẹ lọ siwaju ni ojojumọ aiye, ṣugbọn sibẹsibẹ na, ọmọ-kunrin kanṣoṣo na ni Ọba yi bi, atipe, ọmọ na si jẹ ọmọ kekere. Laiṣe ani-ani, mo ro wipe, ẹnyin na ko ni ṣaile mọ iru ipo ti ọmọ bayi le wa yi mọ.

**ỌMỌ-ỌBA MBA ỌMỌ-TALIKA ṢỌRẸ**

Eyi ti o wa jẹ iyalẹnu nla ninu ọrọ yi ni wipe bi ilu na ti tobi to, ọmọ-ọba ti o jẹ ọmọ kekere yi, ko ni ọrẹ kọọkan rara ni agbo-ile wọn, ayafi ọmọ talika yi. i ja, o si nsọ fun ọmọ rẹ pe ki nwọn ma a lọ sile ọmọ-ọba nitoripe awọn enia rẹ yio ti ma a wa a kiri, ṣugbọn awọn ọmọ yi ko ka ọrọ baba yi kun rara, nṣe ni nwọn sa nrẹrin ti wọ si ṣere wọn bakanna, ṣugbọn laipẹ, awọn ọmọ na sọ wipe,

## ỌRỌ AKEWI

**Lati ọwọ Ọmọ-ọba Akibu Alarape, Ibadan**



AKINBU OLARAPE.

* * *

Awọn ọmọ mejeji yi si fẹran ara wọn, to bẹ ẹ, ti o fi jẹ wipe, ẹnikan ninu wọn ko le ṣe ohunkohun lairi ẹnikeji rẹ. Bayi ni awọn ọmọ yi mba ọrẹ won lọ. Ṣugbọn awọn obi awọn ọmọ yi ko mọ rara, ayafi ni ọjọ kan, ti ọmọ talika yi ṣere ọmọde lọ ṣugbọn nigbati yio pada wa sile, on pẹlu ọmọ-ọba ni nwọn jọ wa sile. Eyi jẹ iyalẹnu nla fun baba ọmọ yi depo wipe, aiya rẹ bẹrẹsi ja, o si mbi ọmọ rẹ lere wipe, nibo ni iwọ ọmọ yi ti ri ọmọ-ọba lati mu wa si inu ile talika bayi?"

**TALIKA FUN ỌMỌ RẸ ATI ỌMỌ-ỌBA NI GARI WAMU**

Ọmọ rẹ si dahun pe, ọrẹ mi t la jijọ ma a nṣere ni gẹgẹbi ẹnyin na yio ti mọ. nṣe ni aiya baba yi sa bẹrẹsi ebinpa awọn, baba yi si sọ wipe, gari laṣan ni on ni nile ati pe ko tilẹ si nkan ti nwọn le fi mu gari na, awọn ọmọ na si sọ wipe ko buru, awọn yio mu gari na.

**ỌMỌ-ỌBA FI AKILAYA-IGBA MUGARI**

Bayi ni baba na bu gari fun awọn ọmọ na pẹlu akilaya igba kanna ti o ni, o si bu omi si i fun wọn, awọn ọmọ na si mu gari yi pẹlu ayọ nla.

**ỌMỌ-ỌBA PADA DELE**

Lẹhin ti nwọn mu gari na tan, nwọn si tu bẹrẹsi ba ẹrẹ wọn lọ titi ti ilẹ fi nṣulọ dẹdẹ, nwọn si ti bẹrẹsi wa ọmọ-ọba kakiri gbogbo ilu. Laiṣe ẹmi ọrọ ni gigun, ilẹ sa su ni ọjọ na ki awọn ọmọ yi to kuro ni ile baba talika yi. Nigbati awọn mejeji si pada de ile Ọba, ariwo ayọ ta gee; nwọn nsọ wipe "Ha! a dupẹ, ọmọ-ọba jaja de".

**Inu Ọba dun, o gbe ọmọ rẹ ati ọmọ talika ka ori-itẹ**

Nigbati ọba foju kan ọmọ rẹ, inu rẹ dun to bẹẹ gẹ ẹ, o si bẹrẹsi bi i lere wipe, nibo ni o ti lọ lati arọ, ọmọ-ọba na si da baba rẹ lohun wipe, on ati ọrẹ on ni awọn jijọ ṣere lọ si ile wọn ati pe, baba ọrẹ on na ṣe itọju awọn lọpọlọpọ. inu ọba na si dun pupọ lati gbọ ọrọ yi lẹnu ọmọ rẹ, o si bi i lere wipe, ṣe ọrẹ rẹ na niyi? ọmọ-ọba na si dahun wipe, bẹni.

**Ọmọ-ọba ko fẹ ki ọmọ-Talika lọ sile**

Ọba na si gbe awọn ọmọ mejeji na si ori-itẹ, nwọn si

(Wo oju ewe kejila)



## Ọba Ọlọkinni fi Tanimọmọ jẹ Ọtun-Ọba

ỌKINNI.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu ti o kọja yi ni Ọba Alaiyeluwa J. O. Ọlanrewaju Keji Ọlọkinni Ọkinni fi Ọgbẹni Samuel Tanimọmọ je Oye Ọtun-ọba niṣoju gbogbo awọn Ọjoye ati gbogbo awọn enia pataki-pataki ilu Ọkinni. Lẹhin ti o fi jẹ oye na tan, o ki i ku ori're o si sọ ọpọlọpọọrọ iwuri nipa Oloye na.

Ninu ọrọ rẹ, Ọba Ọlọkinni so bayi pe:—"Ki iṣe wipe o du oye rara ki on to fi jẹ oye Ọtun-Ọba yi bikoṣe wipe o wuon ṣan an lati fi jẹ oye na ni. Nitorina, ida tio ngbe le e lowọ yi ki o ma fi ṣa on o. Ati wipe ki Oloye na maṣe ri awọn ojoye ẹlẹgbẹ rẹ yoku fin o."

Lẹhin eyi ni Ọba na wa sure fun Oloye titun na pe: Ọlọrun koni jẹki o lu ofin Ijọba ọkọ-ọba ko si ni ṣa a lẹsẹ. iwaju ni ọpa-ẹbiti nre si, ọwọ rẹ yio ma rewaju, yio fi oye na le ọmọ lọwọ. ọba si paṣẹ pe ki Baba-kekere fa a le Mathew Ọlẹlade Oloye Esa Ọkinni, on na si sure fun un. Lẹhin eyi, ọba paṣẹ pe ki Oloye Adeoshun, Ọdọfin Ọkinni fi ewe-oye le Oloye na lori, bi o si ti fi ewe oye le e lori tan ni awọn ọdẹ bẹrẹsi yinbọn, gbogbo enia si fi ilu ati ijo sin Oloye na lọ si ile rẹ.




*Laiyingin rara*

Fun ẹniti o nfi ẹru aje ranṣẹ si oke-okun o ṣe pataki lati mọ daju wipe ẹru aje na yio de oke-okun laiyingin rara. Awọn ọkọ-oju-omi ti Palm Line to ukẹra ni awọn ohun elo to to fun ọja Iwọ Orun Africa nwọn si didi ṣe awọn ọkọ na lati ko onirũru ẹru laiyingin ni Nigbagbogbo, ati ni iye igba kanna loṣọṣu ni awọn ọkọ Palm Line npára ebute ilẹ Gẹsi, ti ilẹ Oyinbo yioku ati awọn ebute Iwọ Orun Africa.



**O ni ifonkanbalẹ ninu lati fi ẹru ranṣẹ nipa ọkọ**

**PALM LINE**

NWỌN NI AṢOJU NI GBOGBO EBUTE PATAKI NI IWỌ ORUN AFRICA

# ALAPARA IBADAN I I

ALAPARA—Olotu tiwa, e ku arọ, a ko jire bi o?

OLOTU—Alafia ni o, ṣe ko sa si nkan?

ALAPARA—Bi kini o jare, baba mi?

OLOTU—Mo woye pe, o dabi ẹnipe oju rẹ rẹwẹsi diẹ.

ALAPARA—Ẹ ṣe pupọ, ẹ ku afiyesi ọran pamọlẹkun-pamọlẹrin kan ni o ti ndamu mi lati bi ọjọ mẹta

OLOTU—Iru ọran wo ni i jẹ ọran pamọlẹkun-pamọlẹrin?

ALAPARA—Nigbati o di ọsan ọjọ Ọjọ'Ilọ ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni ọrẹ mi kan ba wa kesi mipe ki a ṣe ọdẹ lọ.

OLOTU—Iru ọdẹ wo?

ALAPARA—Olotu sa ma a gbọ, mo nfa a bọ e ni ogun ba to bi ọgbọn iṣẹju ki a fi ipade si ẹba-ọna, lati mọ bi onikaluku ti nṣe si ki a to tun ma a ṣọdẹ lọ, bayi ni a fi pinya ninu igbo na.

Nigbati o to nkan bi ọgbọn iṣẹju gẹgẹbi a ti fi adehun si, mo wa si ẹba ọna nigbati o to iṣẹju mẹwa ti mo ti de ẹba ọna ti nko ri ekeji mi yi ni mo ba tun bẹrẹsi i tọpasẹ rẹ kakiri inu igbo na, iyoku ni iregbe mo wa a titi ilẹ fi ṣu nko ri i, nko gburo rẹ.

Ni m oba pada lọ si ile ki emi paapa ma ba a di awati mọ ara mi lọwọ. Nigbati mo de ile, ti iyawo rẹ wa bere lọwọ mi pe ṣe a ri diẹ ṣe loni ati pe kini ṣe ti ọkọ on koi ti de ile tabi o gba ode lọ ni? Mo si dalohun pe oya ọdọ ọrẹ wa kan ni o fẹrẹ de. Nigbati a o kuku ri ikankan pa ni onikaluku wa bẹrẹ si gba alẹgun ara ya nibi ti o wun wa, ni iyawo na ba fi lọ si ile rẹ. mi pe ti ọran ba ri bẹ ẹ, nṣe ni ki emi paapa yẹra kuro ba yẹra kuro ni ile, ọlọpa ni iyawo rẹ yio pe wa mu mi. pe boya mo lọ pa ọkọ on si inu igbo ni tabi mo lọ tan an fun awọnti ngbe enia ṣogun ṣeṣo ni.

Nigbati mo gbọ eyi jẹbẹtẹ gbe ọmọ le mi lọwọ, ọlọ-ntọ bi mo ti pe njade ni ile ni iyawo rẹ tun de, o ni ara ile re ko ma i ti de, ni mo ba sọ fun un pe ki o jẹki nlọ wo o ni ibiti mo lero peo lọ, bi mo ba ba a nibẹ ao jijọ ma a bọ wa si ile, bayi ni mo ṣe ṣe ọgbọn sa mọ obirin ọrẹ mi na lọwọ.

Nigbati o di ọjọ keji ni mo ba tun ko awọn enia lọ si inu igbo nibẹ ni a ba bẹrẹsi wa a kakiri nyoku di iregbe ni irọlẹ ọjọ keji ni deede agogo mẹta ni ẹnikan ninu wa taju kan wo o nibiti o gbe gbe ibọn rẹ ti si ti o fi ẹhin ti igi ni ijoko.

Ere ni, awada ni, nigbati a de ibẹ ni o di on. Njẹ kini o ti jẹ? O ni on ko mọ ọna a ti jade ninu igbo mọ ni. O ni lati ana na ni on ti kirikiri titi ti on ko jana nigbati o rẹ on ni'on wa joko si idi igi pe boya Ọlọrun le ran ẹnikan si on ti yio fi ọna han on., ọkan ninu awọn agba ọdẹ t'a jijọ lọ, si ṣe alaye fun wa pe eweko tabi idariko ni o lu u, nko gbọ iru rẹ ri ni a ba fi mu u wa ile.

Ṣe ẹ gbọ Olotu, nko ni le duro mọ mo tete nlọ, ki nkan wa sọ fun nyi pe on ti mo kan yẹn ti ko fi i fun mi ni aye a ti ma a ba itan emi pẹlu Sariyu Rọtikatika lo ni ọsẹ - yi. O si di ọsẹ miran. O digba ọsẹ o, Olotu oju ko fẹra ku o.



Alapara Ibadan ati Kọtikatika

akeu ejo a maa gbenu iho? owe na jẹ ti ẹnyin agbalagba o. A ni ibọn ṣakabula kọọkan ti temi pẹlu ọrẹ mi yi fi o ma a lọ ṣe ọdẹ, awọn ẹranko keekeeke ati ẹiyẹ nla nigbati owo ba dilẹ.

A wọ inu igbo yi ni nkan bi agogo mẹta abọ ọsan, ati jijọ nṣe ọdẹ ni ifẹgbẹkẹgbẹ kakiri inu igbo, ṣugbọn nigbati o ṣe diẹ ni ọrẹ mi ni on fe gba ọna oke kan lọ, emi na a lọ ni ọna isalẹ ti o ni ilẹ, o ni, nitoripe ti nko

Nigbati o lọ tan, mo lọ fi ọran yi lọ alagba wa kan, ni alagba wa na ba sọ fun

Always ask for
'DE FACTO'
the bread with the appetising flavour

O rọrun to bẹ ẹ pẹlu
Esso AFIKUN

O rọ awamọto lọrun
Esso nfun ni ni AFIKUN iṣẹ





O rọrun fun ẹngini rẹ
Esso nfun ni ni AFIKUN aabo

O rọrun fun apo rẹ
Esso nfun ni ni AFIKUN ere owo



... ma a lo Esso nigbagbogbo o ni AFIKUN ire!



Yika gbogbo agbaiye awọn oniṣowo ESSO ti nwọn wa funra ara wọn nfun ni ni AFIKUN iṣẹ daradara

ESSO WEST AFRICA INC.

## AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ile Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọ o sowọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdale Yoruba. A o si tẹ ẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU

## Dọkita Oyejọla ku

## Oloye Akintọla lọ ṣe idupẹ ni Ṣọọṣi ati Mọṣalaṣi



Oloye Akintọla ni o joko ni arin awọn Musulumi, Ataoja Oshogbo ati Iemọmu-agba ni o joko lọtun, losi rẹ, nigbati Oloye Akintọla lọ ṣe idupẹ ni Mọṣalaṣi Jimọh Oshogbo fun idupẹ aye Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Oorun ti o de.



Oloye S. L. Akintọla ati iyawo rẹ ni o nkọrin ninu Ṣọọṣi yi pẹlu awọn alabaṣẹyẹ, nigbati o lọ ṣe isin Idupẹ ninu Ṣọọṣi All Saints Anglican Church Oshogbo fun ti aye Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o bọ si.



Nigbati Omidan B. Latọja ngbe ẹbun Bibeli mimọ fun Oloye S. L. Akintọla ninu aseye kan ti nwọn ṣe fun Iaipẹ yi fun aye Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o de ni akinrin nṣ sọ fun pe "Wura ati Fadaka emi ko ni, ṣugbọn ni oruko Oluwa gba ẹbun Iwe-Mimọ yi".

## Mathew Neyẹ filẹ ṣaṣọ bora






**Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun**

**OSTERMILK**

njẹki ọmọ-ọwọ
nitẹlọrun!
lagbara!
lokun ninu!




**OSTERMILK**

# ITAN IṢẸDALẸ ILU MODAKẸKẸ

( Lati Ọwọ:- Mudaṣiru Babayode; Ọdọfin—Ologun, Ikare. )

### MODAKẸKẸ SEGUN OKE-IGBO ATI IFẸ PAPỌ

Lehin ọgbọn ọdun (30 years) awọn ara Oke-Igbo wa ran Ifẹ lọwọ won si tun gbogun ti Modakẹkẹ, ṣegun Ifẹ lasiko na.

Nigbati awọn Modakẹkẹ ri i pe awọn tun ṣegun wọn, ni nwọn wa nta wọn lẹru, nigbati ara awọn Ifẹ ko gbaa mọ, ni nwọn ba tuka lọ si Oke-Igbo, Isoya, ati bẹbẹ lọ.

### ALAFIN ATIBA SỌ ... MODAKẸKẸ DI OMINIRA NI ỌDUN 1854

Nibẹ ni wọn wa titi fi di ọdun 1854, nigbati Alafin Atiba wi fun Ogunmola Ibadan pe ki o mu Ifẹ pada o si ṣe bẹẹ. Ifẹ ṣe ileri pe gbogbo nkan awọn ti o wa lọwọ Modakẹkẹ, awọn ko ni bere, ṣugbọn lehin ti nwọn pada de ni awọn Iyawo wọn pada wa ba wọn.

### ILU MODAKẸKẸ NI ỌDUN 1909

Lati igbana ni Modakẹkẹ ti di ominira (Independent) titi fi di odun 1909 ti ilu Modakẹkẹ tu.

Modakẹkẹ pẹlu Ifẹ si jọ ngbe pọ to bẹ ti nwọn nfẹ ọmọ ara wọn ni iyawo.

### MODAKẸKẸ SEGUN IFẸ NIGBA OGUN EKITI-PARAPỌ

Lẹhin eyi ni ogun Ekiti-Parapọ bẹrẹ. Ifẹ kọkọ ngbja Ibadan, ṣugbọn nigbati Arẹ Olubadan igbana fẹ fi Ayikiti je Oni fun awọn ara Ifẹ pẹlu ipa, wọn fi Ibadan silẹ, nwọn si ngbija Ekiti-parapọ.

Nigbana ni Ifẹ ati Modakẹkẹ tun pade ija. Modakẹkẹ si tun ṣegun Ifẹ.

### IJẸSHA, EKITI ATI IJẸBU RAN IFẸ LỌWỌ

Nigbana ni Ijẹṣa, Ekiti ati Ijẹbu wa nran Ifẹ lọwọ awọn ara Ibadan na si nran Modakẹkẹ lọwọ, ogun yi le fun Modakẹkẹ ṣugbọn nwọn mba ija na lọ titi ti ija na fi pari ni 1888.

Awọn Balẹ ti nwọn jẹ ni 1909 titi di 1918 ni wọnyi:- Wingbolu, Fabunmi, Ojo Akitikori ọmọ Aserawọ, Katanbi ọmọ Wingbolu, Ogunwọle ati Akinsanya.

Ni aiye Akinsanya ni Modakẹkẹ tu gẹgẹbi adehun ti nwọn ṣe pe bi Modakẹkẹ ko ba fẹ wa ni abẹ Ifẹ nwọn nilati kuro ni ilu wọn.

Awọn Ifẹ papa ko fẹ ki Modakẹkẹ kuro mọ ni akoko ti a nwi yi nitoripe, nwọn ti wọ inu ara wọn.

Ṣugbọn Oni igbana ti anpe ni Adenẹkan ni o mura si ọrọ a lọdọ awọn Ijọba ti nwọn fimu Balogun ati Ọtun rẹ lọ si Ibadan.

Lakoko yi ni Ifẹ wa nyọ Modakẹkẹ lẹnu to bẹẹ ti nwọn ko fi gbọdọ ri wọn ni igboro Ifẹ.

### AJẸLẸ FUN IFẸ L'AṢẸ PE KI O LE MODAKẸKẸ JADE

Ajẹlẹ Oyinbo ti owa ni Ifẹ nigbana paapa fi ọwọ si i pe, ki awọn Ifẹ ma a fi iya jẹ ẹnikẹni ninu awọn Modakẹkẹ ti wọn, ba ti fi oju ri.

### MODAKẸKẸ TUKALỌ NI ỌDUN 1909

Nigbati awọn ara Modakẹkẹ ri i pe iya na pọ, ni nwọn ba fi ilu silẹ ni ọdun 1909; apakan lọ si Owu, Ipole, Gbọngan, Ẹdun-Abọn, Ẹdẹ, ṣugbọn pupọ ninu wọn ba Akinsanya Balẹ igbana lọ si Ọdẹ-Omu, nitoripe nibẹ ni Ibadan ti pese silẹ fun wọn. Ohun ti o fa a ti wọn fi npe ibẹ ni Ọdẹ-Omu nipe:- Odo kan wa nibẹ ti awọn ara Modakẹkẹ joko ti, ṣugbọn Odo na ki i ni omi ninu nigba ẹrun ti awọn ọdẹ le ma mu, ni wọn ba fi npe ibẹ ni "Ọdẹ-komu."

### ỌBA ADERẸMI KO FẸ IYỌNU

Lehin eyi ni a tun Modakẹkẹ tẹ ti o si wa ni abẹ Ifẹ. Nwọn ri iyọnu pupọ labẹ Ifẹ nipa Isakọlẹ, ọrọ na di ẹjọ ilu Oyinbo ki oto pari. Ọba Aderẹmi ko fẹ iyọnu fun Modakẹkẹ nitori ti ojẹ enia rere ati pe omo Ọyọ ni iya rẹ.

Ṣugbọn "kogbona, ko tutu" ni ọrọ Ifẹ ati Modakẹkẹ titi di ọdun 1952, to bẹẹ ti ọrọ wọn na fi jade ninu iwe Irohin kan ti a npe ni (West African Vanguard) ni 27th June 1952.

Oyesiji ti o jẹ Balẹ Modakẹkẹ ni asiko igba na ko mọ nkan kan nipa ọrọ 1952 yi nitoripe ni Ọdun 1951 ni o fi aiye silẹ.

Gẹgẹ bi nwọn ti sọ fun wa ninu oṣu kejila ni pe o ku ni December 7th 1951. Lẹhin rẹ ni Oyeyemi jẹ oye Balẹ Modakẹkẹ.

Bayi ni itan Modakẹkẹ pari.

Mọdupẹ lọwọ ẹyin agba gba ti ẹṣe wahala nipa itan yi.

Ki Oluwa majẹ ki agba ki otan ni orilẹ iadlai.

Mo si dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti wọn gba mi lati sọ itan yi.

Oluwa ko ni doju ti yin O. Eko ni lu fin Ọlọrun ati t'enia o.

O digba kan na o.

ewfbke.d eatoin shrdluẹmẹ

# KADARA ẸDA

LATI OJU EWE KEFA

Iwọ yio ri i pe owo yio ma wa a kiri ni! Ronu rẹ ki o si ji giri, ṣiṣẹ pẹlu aikarẹ, otitọ-inu, ati ifarada, o si da mi loju pe bi o ba ni suru o nilati de ebute rẹ, si ni ohun ti o nfẹ (Aye ko si fun mi to ninu iwe kekere yi lati ṣe alaye kikun nipa ọrọ yi, mo fi ọrọ yioku silẹ fun iwe ti yio tobi ju eyi lọ).

### MA RONU KI O SI MA HUWA BI OLOWO

Wayi o, ẹnikẹni ti ba nfẹ lati di olowo nilati kọkọ jẹ olowo ati ọlọrọ ninu ero, ọrọ, ati iṣe rẹ. O nilati ma a ronu bi olowo ki o si ma huwa bi olowo. A ti gbọ wipe ẹniti o ba ṣe alaini ni okan, on na l'o nṣe alaini ni apo. Bi enia ba saba nronu pe talaka ati alaini ni on, dajudaju ero rẹ yio sọ ọ di talaka ati alaini. Bi o ba ri enia ti Ọlọrun bukunfun diẹ, ti o ni owo niwọntunwọnsi, ṣugbọn ti o fmran lati ma wọ ekisa aṣọ tabi aṣọ ti ko dara, bata ti o ti ja, tabi ti o ma njẹ onjẹ ti ko dara—boya nitoripe o lahun tabi pe"ẹru mba pe awọn ọta on le pa on l'ara bi nwọn ba mọ pe on ni owo—iru ẹni bẹ nṣẹwọ si iponju, o si le ku sinu iponju ati aini.

Ṣugbọn bi o ba le ni itẹlọrun pẹlu ibukun kekere ti Ọlọrun ba ṣe fun o, ti o si nṣe be ẹniti o ni ibalẹ okan, dajudaju bẹ na ni yio ri. O nilati ma jade ki o si ma rin irin ẹniti o ni owo (jọwọ ranti pe o le wọ aṣọ onisile mẹta ọpa ki o si dabi ọlọla kan ninu rẹ, ki ṣe ọranyan ni pe ki o lọ je gbese aṣọ ti owo rẹ ga pupọ). Bi a si ti nri bata oni ponun meji-abọ titi lọ si ponun marun ṣile marun, bẹ na ni a le ri bata ti owo rẹ ko ju ponun kan-ṣile-kan titi lọ de ponun meji ṣile meji lọ. Nitorian, a nilati ma ṣe ohun gbogbo ni iwọntunwọnsi, ki a ma wa ni mimọ igbagbogbo.

(KOI TI PARI)



# NELSON-COLE DI ALAMOJUTO IJỌ JEHOVA



EKO.

NÍ deede ago meje alẹ ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kewa oṣu yi ni Eni-ọwọ-julọ Bisọbu J. F. Ogunko, Olori Alufa Ijọ 'U.N.A. Church Mission' fi Alufa Arthur Ọlawale Nelson-Cole F.R.S.A.; FRGS jẹ oye Alufa Alamojuto Ijọ 'Jehovah Shalom Cathedral' ti iṣe olu Ijọ 'UNA'

Ki o to o to agogo meje alẹ ti nwọn fi isin iñjoye na si ni inu gbogbo Ṣọọṣi na ti kun toke-toke ati ita ṣọọṣi na kun fun awọn alabaṣeyẹ. Awọn Alufa ati Ẹgbẹ Akọrin si to wole pẹlu orin "Ẹ wolẹ f'Ọba Ologo Julọ". Lẹhin adura, nwọn ka ẹkọ lati Timoteu Kej, ori kẹrin, ẹsẹ kini de ẹkẹjọ. Lẹhin na nwọn tun kọ orin kini 'Ẹmi ọrun gb'adura wa'.

Lẹhin eyi ni nwọn wa bẹrẹ eto iñjoye sinu Ṣọọṣi na. Olori Alufa Ijọ na, Bisọbu Ogunko si bere ori-ṣiriṣi ibere lọwọ Alufa titun na, Alufa titun na si dahun gẹgẹbi o ti lọ ati bi o ti yẹ ni Bisọbu na fi Aṣẹ Amojuto ṣọọṣi na le Alufa titun na lọwọ.

### ỌRỌ IYANJU BISỌBU LORI IFIJOYE NA

Eni-ọwọjulo Bisọbu J. F. Ogunko sọ ọrọ aponle pupọ nipa Alufa Arthur Ọlawale Nelson-Cole. O ni ọmọ ologbe Lọya Nelson-Cole, ọkan pataki ninu awọn lọya Eko ni aiye atijọ ni i, o ni nwọn bi Alufa titun na dada ni gbogbo aye ti nwọn fi mbi enia. O ni o mọ iwe dada, o si ṣiṣẹ labẹ awọn Ẹgbẹ Oniṣowo Reluwe, o si mojuto iṣẹ rẹ dada nibẹ tobẹ gẹẹ ti o fi wa ni aye giga ti a le jowu rẹ. O ni nitoripe Alufa titun na jẹ olufọkansin ati olododo enia ati oniwa pẹlẹ ni o ti ṣe fi iṣẹ Reluwe silẹ wa ṣiṣẹ Ọlọrun.

Lẹhinna ni nwọn fi adura pari isin na nwọn si gba owo-ọpẹ. Lẹhin ti Olori Ijọ na ti fi 'Ore-ọfẹ'' pari isin na tan ni nwọn kọ orin 'gbogbo ogo iyin ọla' to jade lẹsẹẹsẹ. Ki Oluwa ki o pẹlu Alufa titun na ki O si fi idi Ijọ mulẹ.

# Awujalẹ Ijẹbu-Ode ṣe ibura, o wọ Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun

IBADAN.

NIGBATI o ku diẹ ki nwọn pari Ipade Igbimọ Ijọba Ipin Iwọ-Orun ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni nwọn ṣe eto ẹyẹ ibura fun Ọba Alaiyeluwa Sikiru Adetọna, Ogbagba Keji, Awujalẹ Ijẹbu-Ode titun to ṣẹṣẹ joye, o si di ẹkan ninu awọn Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun. Nigbati Ọba na pada de Ijẹbu-Ode, o mura, o we lawani funfun-nini, o lọ kirun idupẹ igori oye rẹ na ni Mọṣalaṣi Jimọ Ijẹbu-Ode.

Lẹhin ti nwọn kirun idupẹ na tan, Ọba na si bẹrẹsi dupẹ lọwọ ọgunlọgọ awọn Musulumi bi ẹdẹgbaasan enia (17,000 people) ti nwọn wa ba a kirun idupẹ nā lati gbogbo agbegbe Ijẹbu-Ode.

O ni on dupẹ gidigidi lọwọ gbogbo wọn fun aduroti wọn ati ifẹ-inu-rere ti nwọn fi ba on ṣe ẹyẹ nigbati nwọn nfi on han ara ilu ati igbati nwọn nde ade, on si tun dupẹ fun ifẹ ajumọṣepọ gbogbo ara Ijẹbu-Ode. O si da ponun meji ṣile meji (£2 2s.) owo idupẹ fun atunṣe Mọṣalaṣi na.

# Ẹni ti ko fẹ ni

**(Lati oju ewe karun)**

bẹrẹsi jijọ ṣere titi, ṣugbọn ngbati ilẹ bẹrẹsi ṣu, ọrẹ ọmọ-ọba yi sọ wipe, on fẹ ma a lọ sile ṣugbọn ọmọ-ọba yi sọfun baba rẹ wipe on yio tẹle ọrẹ on lọ lati lọ sun ni ile wọn, bibẹẹ si kọ ayafi ki ọrẹ on na sun ni ọdọ on.

Ẹ ṣe e pupọ, Olotu ajinde ara yio ma a je o Ki a si ma a fi gbogbo iyoku ti di ọjọ miran ọjọ re o, ọmọ-ọba nrele o, o digba.

# Ẹgbẹ Ire Youths improvement Society ṣe ipade

Ire.

LAIPẸ yi ni awọn Ẹgbẹ Ire Youths Improvement Society ṣe ipade pataki kan gbogbo awọn ẹka ẹgbẹ na ti o wa kakiri awọn ilu Naijiria ni o yan 'ikọ wa. Ọgbẹni M. A. Adediji ni o ka iwe ayẹsi ikini ku abọ awọn ikọ ẹgbẹ na, Ọgbẹni A Jayi, Ikọ ti ẹka Ibadan ni o fesi si iwe ayẹsi ikini ku-abọ na.

Ẹni-ọwọ Alufa E. A. Omilade- si ba apejọ ipade na sọrọ inu awọn ero ipade na si dun pupọ lati gbọ ọrọ iwuri ti o sọ fun wọn. Nwọn si ki awọn ẹka ẹgbẹ ti ilu Ire fun iṣẹ aṣe yọri ti ile-iwe ti Ire Baptist High School ti nwọn kọ. Awọn ẹgbẹ na si nwọn a fun awọn ọmọ ile iwe bẹ ti o ba ṣe dada julọ ni ẹkọ ọfẹ.

Awọn oloye ẹgbẹ titun ti nwọn yan fun ọdun yi niyi: —Ọgbẹni E. A. Lagunju—Alaga; Ọgbẹni M. A. Adediji —Akọwe ẹgbẹ; Ọgbẹni Salu Adenihun—Akapo; Ọgbẹni Adediji Adewale—Ajẹri iwe owo; Alufa J. A. Ebo—Akọwe eleto.

Ọgbẹni Adedeji Adeyeye—Akọwe ilọsiwaju ẹgbẹ ati Omidan M. M. Mofọlaṣayọ Akọwe itọju owo. Nwọn si tun damọran pataki fun Idagba-soke ilu wọn ati ẹkun ilu Ifẹlodun.



Aworan yi ni ti Awujalẹ Ijẹbu-Ode ati awọn ẹmẹwa rẹ lọtun-losi lẹhin ti nwọn nkirun idupẹ tan ni Mọṣalasi Jimọ Ijẹbu-Ode laipẹ yi. Awọn enia ja-nkan-ja-nkan ti o wa pẹlu rẹ na ni, lati ọwọ osi:- Alhaji Adeṣọye Adesanya, Oloye Odutọla, Ọlọla Ayọdele Okusaga, Minista Alamojuto Eto Ẹkọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, Ọgbẹni S. O. Shonibarẹ, Ọga-Agba Alakoso Ile-iṣẹ Amalgamated Press Ltd l'eko, Oloye Olisa Ijẹbu-Ode ati Ọba Alaiyeluwa Ebumawe Agọ-Iwoye.

# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Raji Ayan Bello sọmọloruko

KADUNA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹkanlelogun oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Raji Ayan Bello ṣe ikomọjade ọmọbirin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ Sifawu Abẹkẹ lọrẹ. Alfa Muhammad ni o kirun Wutuba isọmọloruko na ni ọna ẹsin Musulumi, nwọn si sọ oruko ọmọ na ni Amudatu Abẹjẹ, ṣugbọn nwọn sọ eto inawo di ẹhin aawẹ.

Nigbati o di ẹgbọn oṣu kanna lẹhin ti nwọn kirun aawẹ tan ni baba ọmọ na ati gbogbo awọn ẹbi rẹ tun pe gbogbo enia jọ lati ṣe inawo ikomọ ọmọ na, nwọn si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo wọn lọrun. Awọn Ẹgbẹ Ijọ Musulumi Ogbomọsho ṣe ọpọlọpọ adura fun ọmọ na ati baba rẹ. Awọn Ẹgbẹ Majimudini ṣe ere ariya. Alfa Lasisi Akewu-kewe si fi orin aladun da gbogbo enia lara ya lati inu rẹkọdu.

Diẹ ti aye wa fun ti a le daruko ninu awọn alabaṣẹye ọjọ na ni awọn Ọgbẹni B. Oyewọ, O. Atanda, J. Olawuyi, J. Ajao Brother, S. Titilọla, awọn arabirin Asiyawu O. Oyejọju; Muniratu Abio, Rafatu Apinkẹ lati Kachia. Ki Oluwa da ọmọ na si, ki o si fi rere kari gbogbo awọn alabaṣẹyẹ na o.

## AWỌN ỌMỌ IRE OKE OKUN ṢEPADE

AKIM-MANSO-GHANA.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkanlelogbọn oṣu kini ọdu nyi ni awọn ọmọ ilu Ire ti o wa ni Oke-Okun (Ghana) ṣe ipade ni ilu yi, awọn Ikọ si wa si ipade na lati igun mẹrẹrin ilẹ Ghana, awọn ọmọ Ire ti o wa ni Akin-Manso ati agbegbe rẹ si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo wọn lọrun.

Nigbati nwọn bẹrẹ ipade, iṣẹ ti nwọn kọkọ ṣe ni pe, ipade na ki Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinle Iwọ-Orun ku ori're fun ti aye Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o de, nwọn si tun ki Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria fun iṣẹ ribiribi ti o nṣe ninu Igbimọ na.

Awọn ohun pataki ti nwọn ṣe ipade na lelori ni pe, nwọn bẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ki o jọwọ fun awọn ni omi-ẹrọ ni ilu Ire nitoripe idaamu aisi omi ma a nwa ni ilu awọn ni igba ẹerun, ati pe, awọn fẹ ki Ijọba ba awọn mojuto ija ti o wa lori Oye Esa lati ọjọ pipẹ ki nwọn si pari rẹ nitori ọtẹ ko dara ni ilu. Nwọn si pari ipade na pẹlu alafia.






## Ọmuti Afọju kan na ẹnikan l'ọpa, o fi £5 tanran

LAFIA.

LAIPẸ yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Lafia da ọkunrin afọju kan, Malam Areh Moega lẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun ni Kotu pe, o ṣe ijọngbọn, o si mọomcdọgbẹ si ẹnikan. Ega Indu lara, o si ṣe idajọ pe ki ọdaran na lọ fi pọnun marun (£5) tanran si Kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu meji dipo rẹ.

Adajo na tun sọ siwaju pe k iọdaran afọju na lọ san pọnun meji ṣile mẹrin (£2. 4s.) owo itunu fun Indu. Ẹjọ ti ọlọpa ti o ba ọdaran afọju na ṣẹjọ ro ni pe, lẹhin ti ọdaran na ati Indu ti mu ọti yo tan ni Isọ-oniburukutu ni ede-aiyede kan ba ṣẹlẹ larin wọn, o si na ẹnikeji rẹ na lọpa.

## Aṣoju awọn Oniwe Irohin Agbaiye de si Kano

KANO.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrinlelolgun oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Ignatius A. Atigbi, Alabojuto ati aṣoju awọn oniwe irohin agbaiye (Reuters) ni Naijiria de si Kano nipa iṣẹ rẹ. Ọgbẹni D. A. Ibilọla ti awọn Ẹgbẹ Onişowo 'Mobil Oil', Kano ni o si gba a lalejo.

IROHIN YORUBA

# Ijọba Naijiria na £4,000,000 lai gba aṣẹ

EKO.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kokanla oṣu yi nigbati Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ṣe ipade ni Ọgbẹni A. M. A. Akinloye, Aṣoju Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) fun Ibadan ṣe ibere kan pe, elo ni owo ti Apapọ Ijọba Naijiria fi awọn iwe-aṣẹ (special warrants) gba na jẹ, Oloye H. Omọ-Osagie, Akọwe ni Igbimọ Ile-iṣẹ Alabojuto Eto Owo Apapọ Ijọba Naijiria si fi esi pe, aropọ iye owo ti Ijọba ti fi iwe-aṣẹ gba lati ọdun keji sẹhin (1958) jẹ £4,227,485. O ni on ko si le sọ bi Ijọba ba ti na gbogbo rẹ tan tabi koi ti na a tan.

AWOLOWO NI KI IJOBA YAN OBA IBILẸ SAYE GOMINA AGBA

Igbimọ na tun ṣe ipade ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kanna, Awọn Igbimọ Fi-funni (Comittee of Supply) si ṣe aṣaro lori iye owo ti nwọn yio bu fun ile-iṣẹ Gomina Agba lati na, nigbati Oloye Anthony Enahoro, Aṣoju Ẹgbẹ Afẹnifẹre fun ilu Ishan si ṣe ibere pe tani yio rọpo Ọlọla James Robertson, Gomina Agba Apapọ Ijọba Naijiria nigbati aye rẹ ba ṣi silẹ.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria si da a ni 'mọran fun Ọlọla Abubakar, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria pe ki nwọn yan Ọba Ibilẹ Naijiria kan si aye na, o si ni Ọba Sokoto tabi ti Kano lọ si i.

## Awọn Atọkun Egungun ṣa Egungun pa

EKO.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi nigbati awọn egungun meji pade ara wọn ni adugbo Oshodi, ni awọn atọkun ekini ati ekeji gbogun ti ara wọn, nwọn nfi awọn paṣan, kondo ati ọbẹ-alagoro ṣe ara wọn ni ọṣẹ.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ro ni pe, nigbati 'Egungun Bamgboṣe' ti Ọgbẹni Mufutau Idowu, ẹni ọdun mejidilogbọn, gbe ri i bi gbogbo rẹ ti ṣe di rudurudu si ni o ba fi na aṣala fun ẹmi rẹ lọ si ile kan ti o wa ni 33, Oshodi Street.

Awọn atọkun egungun keji si sare lẹ e, ṣugbọn nigbati ọwọ wọn ko tẹ ẹ, ni nwọn ba fi ṣe ileri fun awọn onile na pe awọn yio wo ile na kanlẹ bi nwọn ko ba le egungun ti o fi ara pamọ si ile wọn jade, lẹsẹkẹsẹ ti nwọn ti ṣe ileri yi ni awọn onile na ba fi le egungun na jade kuro ni ile wọn.

Awọn janduku atọgun egungun keji na si gun "Egungun Bamgboṣe" lọbẹ to bẹ gẹẹ t'o fi ku lẹsẹkanna. Awọn ọlọpa si ti ti awọn enia mẹta mọle nitori ọran yi, nwọn si ti bẹrẹsi ṣe'wadi nipa rẹ lọdọ ọpọlọpọ awọn enia. Bi nwọn ba si ti pari ọran na si, ẹ o ma a gbọ o.




Awọn ọlọpa ti nwọn nyẹ ibiti nwọn gbe ti gun Mufutau Idowu ti o gbe 'Egungun Bamgboṣe' ni nwọn wa ninu aworan yi

## Awọn Ẹgbẹ 'Pepsi Cola' ṣe ipade pelu awọn oniwe irohin

EKO.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kokanla oṣu yi ni awọn oniwe-irohin Naijiria ṣe ipade pelu awọn Ẹgbẹ Onisowo 'Pepsi-Cola International' ni gbongan ile-onjẹ, 'Chez Peters' 6/8, Balogun Square l'Eko lati deede agogo mẹta ọsan titi di nkan bi agogo mẹrin-abọ irọle ọjọ na.

Ni ibi ipade na ni Ọgbẹni Victor Bisi Onabanjọ, ọkan ninu awọn gbajumọ oniwe irohin Naijiria ati ọkan ninu awọn Alakoso Ẹgbẹ Awọn Oniwe Irohin, 'O.A.B. Press Service Ltd.' gbe sọ pe ni ọjọ kọkanla oṣu yi ni awọn ẹgbẹ na ba ọkọ ofurufu de lati ilu Amerika si Naijiria.

Ọgbẹni Bisi si sọ ọrọ apọnle nipa Ọgbẹni John P. Stunton, Ọga awọn Alabojuto Ẹgbẹ Onisowo na. O ṣe alaye ni ṣoki pe iṣẹ oti aladun 'Pepsi-Cola' ni awọn ẹgbẹ na nṣe. Ọgbẹni John B. Stanton si ṣe alaye yekeyeke pe, o ti di ilu mokanlelogorin ti awọn ti da iṣẹ wọn silẹ ati pe nwọn yio si fi ọkẹ mẹtadinlogoji o le ẹgbaarun pọnun (£750,000) da iṣẹ na silẹ ni olu ilu Naijiria.

O ni ọkẹ mẹjọ o le ẹdẹgbaajọ pọnun (£175,000) ni awọn yio fi da iṣẹ kanna silẹ ni Kano, Ipinlẹ Ariwa ati pe ọkẹ meji o le ẹdẹgbaajọ pọnun ni awọn yio tunfi da a silẹ ni Onitsha, Ipinlẹ Ila-Orun. O si tun sọ pe ọkẹ mẹwa pọnun (£20,000) ni awọn yio fi da iṣẹ na silẹ ni Mushin ati pe awọn yio si tun fi ọkẹ mẹwa pọnun da a silẹ ni Ibadan—Ipinlẹ Iwọ-Orun. O ni obi jẹ pataki awọn ohun ti nwọn yio fi ṣe eroja oti aladun na.

Lẹhin alaye rẹ yi ni o wa fi awọn Ọgbẹni Emmet O'Connell (Gbakeji Alaga awọn Igbimọ Ẹgbẹ 'Pepsi-Cola International' ati Alakoso Ẹgbẹ 'Pepsi-Cola Company'); Donald Kandall (Alakoso); Sheldon S. Wilson (Gbakeji Alakoso); V. N. Podlesski (Gbakeji Alakoso); Alexia Leon (Alabojuto Ẹka Ẹgbẹ); Paul D. Davis (Alabojuto Ẹka Ẹgbẹ) Joseph Lowry (Alabojuto Tita-ọja); William Barth (Alabojuto Tita-ọja ati bi Tita-ọja yio ti ṣe losiwaju); William Payne, (Alabojuto Tita-ọja); George Russell (Alabojuto Tita-ọja); ati Haydel White (Alabojuto Tita-ọja) fi han awọn ẹgbẹ oniwe irohin na ki nwọn to o tuka.



Ọgbẹni John P. Itanton, Ọga awọn Alamọjuto Ẹgbẹ 'Pepsi Cola' ni o mba awọn Oniwe Irohin sọrọ ninu aworan yi

EGBOGI TI O DARAJU FUN ỌMỌDE

LO FUN ỌMỌ RẸ




FALEMI STORES 7, Bankole Street Phone 20496, LAGOS. O wa fun tita kakiri Ile-Egbogi

Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 5/7, Apongbon Street, Lagos (Editorial) and Advertisement Office) Telphone 23675, 23676. Fun owo "Irohin Yoruba" ọdun kan, Eko sile mẹjọ ati kobo mẹjọ (8/8d.), Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile mẹtala (13s.) Olotu S. M. ADEMUYIWA, 2 Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin